Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia L'oja o ta.

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI-L'EJO

Aki e i Pataki

A fiwe y i ṣe ikede si awon Aṣoju iwe irohin Elet Ọfẹ kakiri agbaiye wipe, enikẹn ti ko ba fi owo ti o ti jẹ ranṣẹ si wa, o pe lejọ, ako si ni fi iwe irohin ranṣẹ si enibẹ mọ.

VOL. XI No. 620. LAGOS, SATURDAY, APRIL 18 — APRIL 24, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)

# Obinrin Kan Bi Abami Omo L'agegbe Igbo Ora.

**IGBO-ỌRA. A gbọ irohin wipe ninu oṣu ọdun titun ni obinrin abọrịṣa kan ti o mbọ Iroko igi bi ọmọ rebete kan. Nipari oṣu January ọmọ ua bẹrẹ si joko, o si bẹrẹ si rin ninu oṣu February, ko si mu'yan mọ.**

Ninu oṣu March lo bẹrẹ si lọ ṣere kiri, gbogbo awọn ọmọde ẹlẹgbẹ rẹ ati awọn to julọ si ntẹle lẹhin kakiri, nigba gbogbo lo nko wọn lọ sidi Iroko iya rẹ, ko kuku ga ju ẹsẹ kan abo lo, agbara ọmọ na pọju ti agbalagba lọ.

Laipẹ yi lo fi ẹsẹ gba ọmọ ọdun marun kan ninu ti eleyini si daku lọ gbọnrangandan.

Nigbati ijọba gburo nipa ọmọ yi ijọba ni ki awọn ọlọpa lọ mu wa, ṣugbọn o kọ lati ba wọn lọ ni awọn ọlọpa ba gbe e kọrun.

Bi nwọn ti gbe de ọhun, pi! lo fo silẹ ti o si nsare lọ, nwọn ko si le ba titi o fi ko wọ inu iroko ni awọn Ọlọpa ba dẹhin lọ mu iya rẹ. Awọn ọlọpa si nwadi lọwọ.

## GOMINA AGBA ILẸ NIGERIA



Ẹniti a nwo yi ni ọlọla Sir James Robertson on ni yio ṣe Aṣoju ọba Gẹsi nibiti nwọn yio gbe ṣe awuyewuye fun ọjọ ibi ọba na nilu Eko ni ọjọ Alaruba, 22nd oṣu April 1959.

## Oro Ilu Kenya Koi Rogbo

A gbo irohin lati ilu oyinbO wa wipe awon ara ilu Kenya ranri bi ọmọ alanda mo awon Gesi lowo, oro na si wa le koko bi oju eja.

Asiwaju awon Oselu ile Kenya ti o nje Mboya so wipe enikan ko le fi agbara te ori won ba fun apapoṣe ilu (Federation) ayafi bi awon ba gba lati ṣe be funra won.

Nitorina, awon kesi ijoba Gesi ki nwon ma tele oro igberaga ti Sir Roy Welensky so nipa won ni ojo die s'ehin wipe ki nwon fi han gedegbe pe ko ni si idande fun ilu Kenya ni odun ti o mbo.

## Ebun Owo Fun Awon Osise



Oloye, Akintola ti a nwo ninu aworan yi so wipe on lodi si ere pe ki awon agbanişişẹ ma fi owo italorẹ tun awon osisẹ kan ti ko da işẹ sile lẹnu ṣe lasiko ti awon osisẹ ile işe kan ba da işẹ silẹ eyi jẹ iwa ti ko dara.

## Olopa Ji Basikulu Egbe Re

PORTHARCOURT. A gbọ wipe Olopa kan ti a npe ni Opuna ni awon olopa ẹgbẹ rẹ gbe duro niwaju adajọ fun ẹsun wipe o ji keke Bicycle ti owo re je Poun mejilelogun abo ti o je dukia ti Ọlọpa ẹgbẹ rẹ kan ti o njẹ Green Nwakinta.

Owe awon agba kan so bayi pe Ṣango ni yio pa Sango, Ọya ni yio pa Ọya, bi adiẹ ba njẹ fun ara won, ko nse ẹriwo.

A gbo wipe Ọlọpa ti nwon mu ni ole na so pe, ki nwon ṣe on jẹjẹ nitori on ko jẹbi rara. Sugbon alatako re so pe ninu sobu awon Ọlopa ni kẹkẹ na wa ki Opuna to wa ji gbe ni ọjo 23rd Osu Feb. 1959 Adajo yẹ ejo na si ojo Friday 8th Osu May 1959.

## Ogun Da Rocha Nja Ran-in Nile

EKO. Nigbati awon akowe Asoju lo sile Ologbe Candido Da Rocha lati lo ko awon dukia ibẹ pamo sọdọ Ijoba titi awon o fi pari eto tani enit o ni ẹtọ lati jẹ ninu ogun Da Rocha ati tani ko tosi.

Ninu yara ti nwon koko si, nisoju awon ti o ni ogun na, awon ri awon nkan oniyebiye ko, gẹgẹbi ehin erin, ati ohun ọṣọ ni nwon ba ninu apoti kan,

Sugbon nigbati nwon kan ile ifowopamosi kan (Safe) ti nwon tẹ ọkọ rọ bọ kọkọrọ na ko le si ile ifowo pamosi na. Ohunkohun ti o wu ti o le wa ninu ile owo na, Asoju yio kesi awon ọjọgbon ile işe P. W. D. lati wa ba won si ile owo na.

Idi re ti nwon se nse onka awon eru ile na ni wipe ki nwon le se iyasoto awon dukia ti o je ti Da Rocha ati eyiti o je ti awon ti o mba Da Rocha gbe. Nitoripe ninu awon ọmọ ti o mba ologbe Da Rocha gbe ti ke si Kotu wipe ki nwon mase ko eru ti on mo ti ologbe na.

## OYINBO BẸRẸ SI GBẸ KANGA EPO MỌTO

Awon Oyinbo elepo, ti a ti ngbero kakiri agbegbe Opobo ati Kalaba wipe nwon ngbẹ Kanga epo Moto, nfẹ bẹrẹ si gbẹ kanga epo moto na ni agbegbe Iwo-Orun ilẹ Nigeria pẹlu.

Ibiti nwon gbe fe gbẹ ofin epo moto na si ni Ito Apata, ni agbegbe Ondo. Awon oyinbo elepo ti o fẹ ṣe işẹ na ni awọn Shell - B.P. Ọkọ ẹrọ ti nwọn fi nṣe işẹ na, nwọn o gbe wa lati agbegbe Kalaba.

## AGBALAGBA JAGUDA W'EWON

ABEOKUTA. Okunrin kan Is motu Akanni ti o ro dede ti o gba dele ninu aso Nylon to jare, eni ti nwon ti ju si ewon odun marun, fun esun wipe, o ji ed-eberin poun (£700) lowo obinrin On sowo kan ti a npe ni Iyafin Rabiatu Seaga n i akoko odun Easter.

Okunrin yi kannani o tun pelu awon egbe olosa kan oruko awon omo egbe Olosa na ni nwonyi- Ladi Ayirde, Joseph Afape' Adekunle Akintoye, ati Daud Aremu. Olopa si nwadi oro won lowo,

## Akowe Egbe Olomi Sanwo Afofojuri

ILORIN. Okan ninu awon akowe egbe olomi (N.P.C.) ni o lo huwa afojudi ninu kotu niwaju Adejo kekere ti a si sa konko poun medoghon mo lara

Okunrin yi ewe, ti mbe labe ofin ti adajo ti se kilo-kilo fun pe ki o lo so agbeje modi, a ko gbodo mu oro re de kotu nitorina o rufin, adajo ni ki o lo san, poun mewa fun eyini.

Oruko akowe egbe Olomi na ni Joseph Idowu Adunkoko. Nigbati ara de e tan, o nlo ba eleri ijoba soro nigbati ejo re si mbe ni kotu ti koiti pari, ow na si je okan ninu awon odaran ejo na.

Adajo ni bi ko ba ri poun medoghon San ki o lo si ewen osu meji.

## Ogboju Olosa W'ewon

EKO. Okunrin tenki Ian t nwon npe oruko re ni David Oyeyinka, ni eniti olopa pe ni ole buruku tabi Ogboju olosa niwaju adajo ni Kotu Yaba, lori esun wipe o gbe eru salo nigbati nwon gba segebi alaru.

Ogbeni Akin William ni eniti o ni eru ti okunrin kandi na gbe salo.


E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE

LOSOSE OKUN FUN IROHIN ALADUN



DA EHIN-DIDUN RE DURO

nipa titete mojuto awon eree inu ati apo-ito re

LO

DeWitt's Kidney & Bladder Pills

Ki o si bo lowo awon irora ti o nko e sinu arun

LAKUREGBE, ARA-RIRO, EHIN-DIDUN ati, Awon IYONU APO-ITO




DeWitt's Kidney & Bladder Pills

L'arin wakati die ni wa a ti Ri ayorisi ise re (Ito a mu awo miran wa)



*We supply steel and reinforced concrete granaries*



*Our deliveries and services include:*

- *designing*
- *supplies of buildi... and assem...*
- *supplies ... and installation*
- *supervision of ... and building wor...*

Please visit our stand at the International Fair ... between June 7th and ...

GEKO EXPORTER OF PLANT EQUIPMENT AND COMPLETE WORKS

Warszawa, Mokotowska 49, Poland

Telegrams: Geko Warszawa Phone: 844-41


## Jomo Kenyata Pada Wale.

KENYA. Okunrin kan ti o je omoba ilu Kenya ti oruko re nje Jomo Kenyata, eniti awon Oyinbo fi sun esun wipe, on lo fi aiya ki awon ara ilu na lati da egbe Mau-mau sile.

Awon egbe Mau-mau yi bere si pa awon Oyinbo ilu Kenya bi enipa adie. Ijoba ile Kenya lepa awon Mau-mau na sugbon nwon ko se fi owo gbendere mu Nigbana ni awon Oyinbo lere pe, Jomo Kenyata yi, bi ko tile ba won lowo ninu egbe Mau-mau, sibe o ni lati je imule egbena nipa be, nwon ba se ejo, nwon si gbe ju si ewon odun meje nitu osu April 1952 sugbon odun marun ni o lo ninu ogba ewon ti nwon fi da sile.

## Ijoba Nwa Oluko Agba Ile Eko Kan

ABEOKUTA. A gbo irohin wipe, egbetale-legberun poun so nu ninu ilewe giga kan ti a npe ni Secondary Modern School Ago-Owu ni Abeokuta, owo na je owo ilewe ti nwon ti ngba jo ti nwon si nfe ko lo si ile ifowopamo ibiti nwon fi pamo si.

Enia o le ti edodo oro yi han, ti o si le fani leyin re ni Oluko agba ile eko yi, sugbon a wa a a ko ri i.

Owo yi je apapo owo ti nwon gba larin odun 1957 si 1958. Awon Olopa ti nwa Oluko agba na, nwon koiti mo ibiti o gbe wa.

## OWO FARANSE TE OKO AWON SEKS

A gbo irohin wipe oko ogun awon Faranse kan ka oko awon Seks (Czechoslovakia mo inu okun Mediterranean ti o nko ota ati etu lo fun Ijoba Moroko nitori awon ara Moroko ti ba awon Seks se adehun lati ko awon ohun ija wa fun won, nwon si ti dina fun oko na Faranse ko gba fun oko na lati koja, bi beko yio ba ara re ni sale okun.

## N.C.N.C. YI EHIN OKU PADA NILU IBADAN



Awon egbe Mabolaje tilu Ibadan ti nwon je alabase kanna po pelu egbe N.C.N.C. yi ehin oku Ologbe Alhaji Adelabu pada nigboro ilu Ibadan, ojo na dabi ojo odun awon Imale. Oba ko fi eri ji ...

# Owe Ile Yoruba

1 Igbin ka, ka, ka, ẹbiti ka, ka, ka, ẹbiti ti ko gboju, ko ni le pa igbin rara Patako Ẹfọn ka, ka, ka, lo nta aja iẹnu.

2 Ika ko fẹ ki a ru ẹru ki a sọ, ori ẹni lo nsọni, nitoripe enia bi aparo ni aiye nfẹ.




## Ija Osanyin Ati Onitumpulu
APA II

(O tẹrẹ lati ọsẹ ti o koja)

Nigbati Onitumpulu ki Ọsanyin mọlẹ, ariwo ta gẹ e e, bẹni a gbo fọ. Onitumpulu fẹ ṣẹ Ọsany'n lọrun, Ọsanyin pe ọfọ, o ni ki abo mu ki o de e lọwọ ati ẹsẹ. Eyiti a nwi yi pẹ Onitumpulu ṣubu lulẹ, ko le gbe apa, ko le gbe ẹsẹ.

Ọsanyin tẹ ọwọ bọ apo o fa ilagba yọ, o si ko patiẹ bo Onitumpulu, o na a, gbogbo ara rẹ fẹrẹ ma ni afo.

Irohin kan lọ ba Oduduwa nibiti o gbe joko larin awọn agba Ifẹ. Bi o ti gbọ ọrọ na, o d'de kan, o mu ọpa alaṣẹ rẹ, o kọri si ode lati lo wo ohun ti o ṣẹlẹ.

Nigbati o yọju s'ode, o ri gbogbo awọn enia ti nwọn lojupọ mọ ara wọn o nwipe, oto! atoto arere! ariwo ko jẹki awọn enia gbọ ohun Oduduwa.

Oduduwa ka eyi si arifin, o nlọ pelu ibinu, o si gbe ọpa rẹ s'oke, o na mọ arin awọn onija ati awọn ọlọja, ọpa na si ba gbohungbohun, Oduduwa ke mọ para, ẹru ba bẹni o se sare wọ igbo lọ. Lati ọjọ na wa ni Gbohungbohun ti nfi ara ṣoko fun enia.

Ọsanyin gbọ ohun Oduduwa, o salọ, ṣugbọn Onitumpulu ko le dide, Odua fi ọpa ọwọ rẹ kan, ide na si ja, o si dide, o ro gbogbo ẹjọ fun Oduduwa, o si da lare pe ki o ma lọ.

Onitumpulu wa pada sile rẹ. Bi o ti dele o ba ilẹ sọrọ pe ki o mu Ọsanyin ki o si de mọlẹ fun ojo meje. Lẹsẹ kanna ni ẹsẹ Ọsanyin ji sinu ilẹ, ko si le fa yọ mo.

Ẹ ma ka iwe irohin Ele-Ọfẹ, ẹo ma gbo irohin bi oro na ti ṣe di ti Dada ati Ṣango.

(Koiti pari)

# ELETI - OFE

A-NJU-WON KO ȘE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

23, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - ỌFẸ LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL. XI NO. 620 SATURDAY APRIL 18 - APRIL 24, 1959


## Suru Ni Baba Iwa

Agba ti o ba ni suru, ohun gbogbo l'o ni-Ọpọlọpọ ẹkọ ni o wa ninu gbolohun ọrọ owe oke wosika wa ọse yi, ti a fi șe asayan ọrọ wa fun ẹnyin ọkawe wa dajudaju bi ẹ ba fi lakaye gbe ọrọ na na ẹo ri wipe ko si ohun ti enia le dawọle ni șișe nile aiye ti a wa yi, ti oluwarẹ ko ba ni suru, nkanna ko ni lo bọsi, tabi ki o șe ni asiko ti oluwarẹ fẹ ayafi ki ẹnibẹ fi suru pẹlu ișẹ rẹ.

Ọrọ pupọ ni o sọ mọ suru ti o si jẹ ẹkọ fun awa ẹda ọwọ Olodumare, ni orișiriși ọna ti awọn Yoruba fi șe adọpe ọrọ ti nwọn npe ni owe. Suru jẹ ohun pataki ti ọmọde ati agba ọkunrin ati obinrin ni lati ni laiye ki aiye le r'oju fun enia bi enia ko ba ni suru, gbogbo ohun ti o ba ndawọle lati șe ni yio ma jẹ inira ati așeti fun ẹnibẹ. Nitorina, ninu ọdun titun ti a șẹșẹ bọsi lẹhin oșu Ramlan ti a fi ajọyọ itu'nu awẹ yi, ẹ jẹki a ni suru nitoripe suru ni ogun aiye.

## Enyin L'o Nd'akuko

Adiẹ mi ti soo ra, mo tọju rẹ, o si dagba. Losan ọjọ kan ti ojo rọ, nko mọ pe, o ti je lọ. O bọ si ko'o, ojo si pa, o wa nke. Nigbati baba mi gbọ igbe rẹ ninu koto, o si ba mi yọ ọ jade. Bi mo ti gbe e soke, ase lo ngbọn. Iya mi ni ki nda ina fun, mo dana fun, o si nya ina. Nigbati o șe oju rẹ wale, o jẹ agbado, o tan bọ sode, o nlọ tan ile, o ye ẹnyin mẹwa opa mẹsan, o si fi ọkan dele, mo ta meji, mo si da ewu kan.






## Irin Ajo Lo Si Meka Ati Medina

(Lati owo Alhaji)

Ti wọn ba gbe ẹru rẹ lọ ma foya rara kole sọnu awọn onibode ko ni Iwe ẹri rẹ Pass port pada fun ẹ rara o. Lẹhina eo wọ mọto "Bus" mọto yẹn yio gbe yin lọ si Mẹdina lati Hujaj ti ẹ ba de ibẹ, eo ri ẹru yin ninu ile Madinatul Hujjaj. yi. O to ibasọ kan si idi ọkọ ofurufu, șugbọn On'-mọto ko ni bere owo lọwọ yin inu ile yi ni gbogbo nyin ti ẹ wọkọ ofurufu ma sun omi wa nibẹ. Ina Lẹntiriki ile iyagbẹ ile iwẹ, Fan ati gbogbo ikan miran gẹgẹbi ile Eko to dara.

Ki ẹ to wọle Madinatul Hujaji yi, awọn kan yio wa ba yin wipe ki ẹ wa parọ owo Gẹsi si ti Larubawa Ẹ ma da wọn lohun, bi ẹ ba da wọn lohun, wọn yio tu yin jẹ. Nitori Riyal mẹwa ni wọn yio șe fun yin ni £1. bi 12 tabi 13 ni £1. Șugbọn owo wọn na nle nigbamiran, bẹ lo si ndin nigba miran șugbọn bo tile din to, ko gbọdọ din ju (11) mọkanla lọ" Riyal duro ni iduro 2s ti Gẹsi ti ẹ ba simi diẹ ninu ile Medinatul Hujaj ti a wi yi awọn Ọlọpa yio wa ba yin wipe kiẹ wa sibi isẹ awọn ki ẹ wa gba Iwe, ẹri yin" Pass Port', ẹo wa san £8. 10s 6d ki wọn to fun yin iyẹn owo mọto ti e wọ lati ile Ibode de ile Madinatul Hujaj ati owo ile ti o san papa ati owo mọto rẹ de Mecca ati owo ijọba Jidda.

Așọ Haraini wa ni jidda owo rẹ si din pupọ si ti Eko Lagos ati aburọda opọlọpọ nkan ti a nsare ra ni Eko ni owo geregere lo wa ni Jidda ti owo rẹ si din pupọ si ti Eko Lagos ilu jidda dara pupọ. Ọja si dinwo pupo ju ti Eko Lagos lọ. Gidda ni Mọșalași Anobi Adam ati sare Awawu gbe wa ki e to fi ilu Jidda sile lati lọ si Mecca eo lo si Mọșalași Anobi Adam ee yan Nafila meji eo șe asalatu eo toro gbogbo ikan ti e ba fe, eo ma wa lo si Mecca nigbana. Jidda si Mecca je ibuso mejilelogoji (42 miles) Buss" moto ni ao wo ako ni san owo moto ni alo si Mecca ati abo.

(Koiti pari)

## Oro Owo Ifehinti Di Jankulubo

ENUGU. Gegebi a ti gbo wipe awon Olotu ijoba Ila-orun ngbero lati se ofin ti yio fun won ni owo afehinti gbigba nigbati nwon ba kuro ienu ise iselu lehin odun marun tabi ju belo.



Eri ni ohun "to fa opolopo awọn enia nibi gbogbo lati se atako si oro na, sugbon Olotu ijoba Ila-Orun," Dokita Nnamdi Azikiwe ti ise Olori "e g b e Alakuko (N.C.N.C.) ti fesi wipe awon yio mu ofin na kuro gẹgẹbi ise ijọba rere to ni lati ma t' eti si ohun awon enia re lati ma se ohun ti nwon ba fe.

## GOMINA IWỌ-ORUN PEGEDE



IBADAN Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Gomina ti ipinlẹ Iwo-Orun, nilu Ibadan, ninu ile igbimo Așofin ni Ọlọla Gomina na ti so ninu oro re lati ori aga-ola wipe ijoba on ti pinnu lati gba ẹnikẹni laye ninu awon ẹgbe Oșẹlu lati șe alaye tirẹ yekẹyeke fun awon oludibo, nitorina, ko ni si idalowoko lodo ijoba Iwo-Orun.

Gomina Sir John Rankine so oro yi larin ajo igbimo awon Oselu ati igbimo awon oba ile Iwọ-orun ki o ma ba si edekoyede ni asiko idibo ti o mbo yi.

# NISISIYI !

FUN IGBA AKOKO NILE NIGERIA . . .

AWON ONISOWO

**THE NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.**

YIO MA ṢE

ETO OHUN IDANA GAS SINU ILE LATI MAFI DANA

Ale fi Gas pẹlu Meter rẹ sinu ile ti a ngbe Koni agbekiri. Ko si ni ṣalai muna wa nigba kan. Ko lewu, o rọrun, lilo rẹ din inawo ku.

ẸNYIN KỌLEKỌLE, ONILE ATI ẸNIKẸNI TI O BA FẸ LILO RẸ KI

O KỌWE FUN ALAYE KIKUN LỌDỌ :-

**NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.**

2, ITAPEJU AVENUE, P.M. BAG 1040 APAPA TELEPHONE 55295.

Iye owo rẹ ati gbogbo alaye nipa re ni ao ṣe fun yin lọfẹ.


# Owe Ile Yoruba

Aiye ko lọra. Gidigidi ko mọla, ka ṣiṣẹ bi ẹru ko da nkan. O wu Aguala ko mọlẹ to oṣupa, Ọlọrun ni ko fifun. Da tọrọ, da tọrọ, agba ti ko ba da tọrọ omi ọbẹ ni yio jẹ. E ke ni yio pa eleke, ọdalẹ a si pa ọdalẹ, a difa fun amokunkun ṣole to wipe oju oba aiye ko ri on. Bi oba aiye ko ri o, oba orun ko ha nwo ọ bi?

Akoko daripọn inu mbi odidere, Iṣe ko gbọ ekun. ebi jare ọle. Igba ojule lo wọle ikan, igba ọna lo wole Awurebe Ajanaku baba nnama.

## "Eniti Olorun Ko Pa Enia Kole Pa"

Lati owo Y. Ade. Buraimoh

**Itan mi na lọ bayi :- Nigba lailai, Baba kan wa nilu yi on pẹlu iyawo rẹ, ilu siniyi bi ẹnikan ba bi ọmo mẹta lẹkanṣoṣo (Ibẹta) aṣo to ba wa lorun oba ilu na ati ohun meremere tio ba fi ṣẹṣo sara yio jẹ ti baba ibẹta baba yi si jẹ agbe oko l'o nro.**

Iyawo Baba yi wa ni oyun sinu Baba yi si jẹ agbẹ (Farmer) o wa di ni owurọ ọjọ kan bi baba yi ti ji o wa na tọtọ, (oyan) o ni aiye on ju ti ọba ilu yi lọ gbigbọ ti awọn ara ilu yi gbọ bẹni wọn fi ori le ile ni, wọn ni lagbaja ni aiye ti on ju ti yin lọ Kabiyesi. Oba ni kinnla lẹsẹkanna oba si ran ni lọ si ile baba yi pe ki o wa ro ti ẹnu rẹ ki on gbọ ṣugbọn wọn ko ba Baba na ni ile o ti lọ si oko.

Bi baba yi ti nlo si oko o fi ese ko, beni ekanna ika baba na nse ẹjẹ wowo, beni Baba yi sope "on sese ndun bo epo ṣubu lu oyin" o fi ori le ona oko rẹ bi o ti de oko rẹ, o si dẹ takute si oko rẹ. Takute yẹn lo kọkọ lọ wo bi o ti dẹ ibi takute, ko ri takute, owo hin-wo ọhun ko ri takute na.

Bi o ti wo ẹgbẹ kan igbe, beni o ri takute re pelu ẹran oya, Baba yi tun sope "On ṣẹṣẹ ndun bọ epo subu lu oyin", enu ti o gbe si oke bayi, oyin lokan si lenu (Honey).

Nigbana ni Baba yi wa bẹrẹ si roko rẹ lọ, bi o ti nro oko re lo, bẹni o kan ẹyin (Egg)apa-Baba yi wa sope, aiye on dun ju ti aiye Ọba lọ, Baba yi bere ise re, o nro oko kuakua-kua, ko pe o kan iho okete kan, kikan ti o kan iho Okete yi, obẹrẹ si gbẹ ! gbẹ !! gbẹ !!! titi o fi kan Okote na, Okete meji lopa ninu iho na, inu Baba yi tun dun bakanna, o tun so gẹgẹ bi o ti ma nso telẹri.

Nigbana lowa mura lati pada si ile rẹ. bi o ti nlọ si ile re, beni ogbo didun ẹiye kan, ti o ndun bayi Oṣorire ! Oṣorire !! Oṣorire !!!. O tẹ eti sile, o ngbọ didun ẹiyẹ yi, o je iyalenu fun gidigidi, toripe ko gbo iru rẹ ri bi o ti n l o beni eiye y i ntele, nigbati o de enu odi ilu ni eiye yi to pada lehin re.

Ki a ma fa oro na gun lo titi o wo ile, bi o ti nwo ile ni won jiṣẹ fun pe. Ọba ran ni de ile nigbati ẹ lo si oko tan oni ki ẹ wa ti ẹ ba ti de. Ọba si ti lero pe, bi o ba ti de bibe ni on yio be lori, bi Baba yi ti de odo Ọba. Ọba ti mura sile, o wo ewu etu nla, sanyan nla. Bata onjyebiye Sokoto, Fila, Oruka ati golu olowo yebiye ti o da s'orun. O si joko si ori a g a.

(Ko iti pari)

# Itan Elegbeje Ado

ELEGBEJE ADO DE ODO IGBALE

Bi jagun ti de ọdọ Igbalẹ y' oki ẹnu bọ ọge de kio to so okan kan, on' Edumare magbagbe mi pẹlu mi. Ọgede bẹrẹ, Iba gbogbo ẹda enia ilẹ aye, iba awọn iya mi oṣoronga, iba Ẹbọra nlanla to pẹlu mi, ẹnu Ewure lo npa ewure, ẹnu aguntan lo npa aguntan, ẹnu otolo lo npa otolo, Ẹbọra Ọṣudun ẹnu rẹ lo pa ọ, ẹyin, igi lẹhin ọgba igbo yi ẹ pẹlu mi gbe ọrọ ebọra yi jade kuro ninu igbo yi gbigbe ti Elegbeje-ado gbe, oki ado kan mo ninu.

O si ngbe lọ ni ọran t awọn ẹbọra inu igi tio ran lọwọ nijẹsi, tio fi ọna ti yio gba han, o ni o tọ ki on lọ fi abọ fun wọn, o si wa ranti ọfọ ọjọ kini, ti wọn fun pe, ti o ba fẹ lati pada wa si ọdọ awọn o wa fi ẹnu le Gunnugun jẹbọ ajẹgbe, akala jẹbọ ajẹpọ, Ẹgbẹn owu ki wa nilẹ ki afẹfẹ fẹ ki o mayira pada oṣewọ gbemi, gbemi, gbemi, bi o ti wi bayi tan o si ri ara rẹni ọdọ awọn ẹbọra na pẹlu igbalẹ ni ode ọdọ wọn.

O ya wọn lẹnu, wọn ni kini Igbalẹ yi ti jẹ ? o dahun oni Ẹbọra ọṣundundun na ni yẹn, wọn wọn si nja ni irọ o ni ododo ma ni, wọn ko gba rara o ni ṣeki on fi han yin nisinyi, gbogbo wọn si dahun p e k o buru. Ṣe gbogbo wa na ni ati mọ pe ti ogun ẹni ba da ni loju, ama fi nsọya ni. O ni ẹ fi oju silẹ, kiẹ woran o.

JAGUN TU ẸBỌRA ỌSUNDUN

Titu ti o tu silẹ, aya on papa ja ko mọ ibiti on wa mọ gbogbo gbogbo wọn si wo o lẹsẹkanna ni o si tun sọdi igbalẹ pada, o tun nmin gẹẹbi ti jọsi o si tun wa fi ado si ninu ko wa mi mọ rara, ẹnu wa ya awọn ẹbọra wọnyi ohun ti Elegbejeado yio kọkọ fọ nipe agbara Edumare nio ati agbara yin na ati agbara awọn iya mi Ọṣoronga papa.

Nigbana ni awọn ẹbọra wa kan sara si Elegbejeado pe ọkunrin okunrin ogun ni iṣe, nigbana ni wọn wa dupẹ lọwọ rẹ pupọ fun ore nlanla 'to se fun wọn nipa mimu ẹbọra buruku yi kuro ninu Igbo Ọṣundundun

(Koiti pari)

# Itan Esin Kiriyo Ati Imale Nilu Eko

Awon Arokin so wipe Orisa ni a ba lowo awon baba wa ti nwon nsin bi, Sango, Ọ atala Eyinle' Ọya, Ọsun, Orisa Oko, Elegbara, Sopọna, Efun Efun, Ibeji, Ori Orisa-koko, Kori. ati awon orisa be. bẹ.

Nigbati isin Imale de, awon Babalawo sọ asotele fun awon ọba gbogbo wipe, isin na ni yio pa gbogbo isin yoku mọlẹ' lẹhin na ni isin Kiriyo de.

Nigbana ni lu Eko, ko si ẹni ti o gbodo la enu rẹ fi perun. Sugbon awon enia nlanla to gba isin Imale, ko gbodo ṣe e ni oju gbangba. Diẹ ninu won ni Pinnisin alagba gbajumo kan ni Ita Alaje, Agarawu, Onipe, Erukebodo Alebiosu, Agoro, ati awon gbajumọ bawonni. Lasiko na ni awon Kiriyo nkorin bayi lati fi ṣata isin Iborisa wipe:-

1. Iku l'a ba bọ, A ba forisa silẹ ojo awurọ. o gbe weli-weli de o.

2. Nigbati'ku npani Ki l'orisa nwo ojo oauro, o gbe weli-weli de o.

bwon kiriyo tun lo tanu b a awon Imale bayi pe:- Anobi le gbojule. Orisa ni nwon fehin ti Onigbagbo fehin ti Jesu, O duro gboin-gboin.

Nigbati ọrọ esin Imale, Kiriyo ati Iborisa wa le kenka tan, o wa di wipe ki awon gbajumo enia bere si sonu larin ilu, ni Imale ati Kiriyo. Ọrọ yi ni Danmole olorin fi kọ orin bayi wipe

Aiye lo pa Pinnisin o, (2 times)
Aiye lo yọ'da to fi p'Agarawu
Eni ba ti sẹ ni'ga ni nwon a mu lo pa. Ti ko mọ di o,
ọpọlọpọ ti ko mo di.
L'aiye ti ran t'Olodumare
Aiye lo pa Pinnisin.


Kere o !

Ati ni orisirisi o g u n German to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7 Egerton Road Lagos







No 5008/2/Vol 11/818.

## Warri Crown Land

The attention of all sub-lessees of Crown Land in Warri is invited to the Western Region Government's announcement dated 26th of February 1959 of its intention to assign to the Itsekiri Communal Lands Trustees Government's rights over certain of the lands in Warri which fall within the Crown leases of 1906, 1908 and 1911.

All sub-lessees of Crown land in Warri are invited to apply or new sub-leases which would be granted by the Trustees for a term of 99 years from the 1st of January 1959 and otherwise on the same terms as the existing sub-leases. Application on the appropriate form should be addressed to the Land Officer, Crown Lands Estate Office, Warri to reach him before the 30th of April 1959. Copies of this notice together with application forms have been addressed to all sub-lessees and additional copies of the form may be obtained from the Crown Lands Estate Office, Warri or the Ministry of lands and Labour, Ibadan.

If no application is made by an existing sub-lessee the concesion of the extended term may be lost.

T. N. ROSSER
Ag. Permanent Secretary,
Ministry of Lands and Labour

26th March 1959

## ELETI - OFE DARABA




# Itan Ajapa Ati Awon Elegbe Re

Lati Owọ
Y. Ade Buraimoh

Itan mi na dori ko dori odori Ajapa ati awọn Ẹlẹgbẹ rẹ laiye ijọun. awọn ẹgbẹ Ajapa wọn ki jẹ ẹiyẹ Agbigbo o wa di ọjọ kan gbogbo wọn wa pe ara wọn jọ wọn se ipade lori ẹiyẹ agbigbo pe ki ẹnikẹni mase ẹiye gbigbo fun awọn jẹ, gbogbo wọn si gba lẹ.

Ajapa si jẹ ki igbo ki igba enia, ki nkọ ki oriki rẹ fun yin na oriki rẹ ni yi :- "Ajapa iruko ẹkọ Yooribo alebẹlẹbẹ maja ọkọ iyagba Ajapa tondara koni omi loju o wa di ọjọ kan on pẹlu ọkan ninu ẹgbẹ rẹ wa nṣe deri si ara wọn Ajapa ni on less ẹiyẹ agbigbo fun wọn jẹ, o ni irọ ni o pa, Ajapa ni on na ? o ni bẹni. Wọn ṣe ileri ni ọjọ na fun ara wọn.

Asiko ọdun wa sunmọ nwọn si ni lati ma da ina odun fun ara wọn, gẹgẹbi ẹnyin na tiṣe mọ gẹgẹbi a ti ma nṣe nisisiyi ni ọdọdun tia ba jẹun ni ile ẹnikan, atun lọ jẹ ni ile ẹnikeji ati bẹbẹ lọ.

Ọdun de, gbogbo wọn ti mura silẹ fun asẹ Ajọdun ti nwọn ma nṣe nigbati o wa ya wọn tun ṣe ara wọn ni iranti nipa ti ẹiyẹ agbigbo ti nwọn ki ijẹ.

Igala ni okọkọ ṣe ase na, nigbati won de ile Igala o se onjẹ ajẹti ni nwọn jẹ, won si mu ọti amu tẹrun, ijo pọ ni ọjọ na ko ṣe ma wi rara. Nigbati wọn kuro nibẹ' wọn tun lọ sile ẹtu. ẹtu elesẹ oje o jẹ arẹwa ẹranko, nigbati wọn de ile rẹ, aṣọ tio da fun awọn awọn iyawo rẹ papa iyatọ lo jẹ, ko ṣe ma fi ẹnu sọ rara, wọn tun jẹ nibẹ wọn mu bakanna.

O wa idi ọjọ keji, won tun lọ si ile egbin, dide ti won de ibe, ko tilẹ yẹ rẹ kia sọ gẹgẹbi ẹranko yi ti dara to mọ, ẹnyin papa na ma nda iaṣa pe "odara bi egbin", ohun ti ẹwa rẹ pọ ni a ma nsọ bẹ fun. Wọn tun jẹ wọn tun mu, iyatọ nitirẹ papa jẹ ninu ode ti niọ, ni ọjọ na Ajapa na fun ara rẹ wa da ọjọ ti awọn ẹlẹgbẹ on yio wa si ile on si ọjọ mẹrin oni mo fẹ lati ri yin ni ile mi, olori aṣọ yin s ni mofẹ kọ lo wa, tia

(Wo yoku loju-ewe kejo)

## Ẹgbẹ Awo Ogboni Ibile Joye Titun Nilu Eko

Ẹgbẹ Awo Ogboni Ibile ti Ajanaku ni No. 53, Okepopo Street, ṣe ipade ifinijoye lọjọ 12th oṣu April 1959, nınu Iledi ti Ajanaku (Ogbe-ate) nwọn si fi enia pataki kan j'oye Apena sinu ẹgbẹ Awo Ogboni Ibilẹ na, oluwarẹ ni Ọgbẹni Fẹhintọla Ọlaitan ti a fi joye lati ọwọ Oloye Onifade, Oluwo Ajanaku Aṣoju Alaga Ogboni Ibilẹ gbogbo Nigeria.



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Onifade Oluwo Ajanaku, Aṣoju Alaga Ogboni gbogbo ibilẹ ti o fi wọn j'oye Apena na.

Diẹ ninu awọn enia ti o wa sibi ẹyẹ ifinijoye na ni Oluwo Akande lati Mushin, Ajile Iya Abiye, lati Iwaya, Johnson Apena, Akọwe ẹgbẹ, Braimọ Oloye Apena ti Isalẹ Eko, Abẹkẹ Tade, Oloye Iya Abiye ti Ajanaku, Abẹbi Ajanaku, Oloye Iyadu, Awawu, Iyalaje ti Ajanaku, Afilaka, Oloye Apena lati Idi-araba, Tinuade, Iya Gbogbo lati Ebutemẹta Asimọwu, Olotu Erelu lati Ikorodu, Oluwo Oṣifuye, Oluwo Ọlọrun-kok'ajo ati ogidinleje awọn enia to wa ti a ko le darukọ.

Diẹ ninu orukọ awọn ọmọ Ajanaku ti o wa sibi ẹyẹ na niwọnyi :-

Ọlaifa Olu, Ayinla Turner, Kọle, Akanbi Fawẹmimọ, Faramọbi, Babalọla, Tiamiyu Iya Ewe ati Fakọlade Ajanaku.

Nwọn j'oye yi labẹ asia Oloye Aminu Kosọkọ Ọlọja Ereko ti iṣe Babasalẹ gbogbo Awo Ibilẹ.

Gbogbo awọn Iledi ti o wa sibi ẹyẹ na jẹ mejidilọgbọn. Oluwo Ajanaku fi ile pọn ọti, o fi ọna roka, gbogbo enia jẹ onjẹ ajẹti, nwọn si mu ọti amugbadun.

Nwọn ṣe ariya titi ilẹ fi ṣu ti o si fi mọ Eku inawo ti oye na, oye a mọri Iledi a gbaye siwaju o.

No. 5008/2.Vol.11/

## WESTERN REGIONAL HEADQUATERS TELEPHONE NUMBERS

The following Telephone numbers in offices occupied by Regional Ministers, Ministries and non-Ministerial Departments are announced for general information:-

PREMIER'S OFFICE
Premier - Ibandan 147
Office staff - Ibadan 911 x and 2350 x

MINISTRY OF AGRICULTURE AND NATURAL RESOURCES
Minister - Ibadan 922 (previously 2211)
Ministry - Ibadan 934x AND 2134 x

MINISTRY OF ECONOMIC PLANNING
Minister - Ibadan 930 (previously 2061)
Ministry - Ibadan 904x AND 2200 x

MINISTRY OF EDUCATION
Ministry - Ibadan 954 x AND 2250 x

MINISTRY OF FINANCE
Minister - Ibadan 952 (previously 2262)
Ministry - Ibadan 911 x AND 2330 x
Accounting Division - Ibadan 970 x AND 2105
Inland Revenue Division - Ibadan 904 x AND 2200 x

MINISTRY OF HEALTH AND SOCIAL WELFARE
Ministry - Ibadan 904 x AND 2200 x

MINISTRY OF HOME AND MID-WEST AFFAIRS
Minister - Ibadan 988 (previously 2326)
Ministry - Ibadan 920 x AND 2320 x

MINISTRY OF JUSTICE
Minister - Ibadan 924 (previously 2285)
Ministry - Ibadan 980 x and 2300

MINISTRY OF LANDS AND LABOUR
Minister - Ibadan 926 (previously 2153)
Ministry - Ibadan 950 x and 2150

MINISTRY OF LOCAL GOVERNMENT
Minister - Ibadan 928 (previously 2284)
Ministry - Ibadan 980 x AND 2300

MINISTRY OF TRADE AND INDUSTRY
Minister - Ibadan 978 (previously 2110)
Ministry - Ibadan 904 x AND 2200x

MINISTRY OF WORKS AND TRANSPORT
Ministry - Ibadan 904x AND 2200x

AUDIT DEPARTMENT
Ibadan 970 x and 2105 x

ELECTORAL COMMISSIONER'S OFFICE
Ibadan 320 and 2057

PUBLIC SERVICE COMMISSION
Ibadan 904 x and 2200 x

REGIONAL LEGISLATURE
Ibadan 960 x and 2160 x

2 Persons calling any of the Ministers or Offices listed above, either over the trunk circuits or from a number on the main Ibadan Exchange, are requested to ask for the FIRST Ibadan number shown in all cases. Persons calling from the Agodi area should ask for the second number shown in each case.

3 In addition to the direct lines, the Pemier and Ministers can be obtained by calling the appropriate P. B. X. number.

x Indicates a P. B. X.

SGD ? ? ? ?
Secretary to the Premier
and Executive Council


ARADAN NERVIGORA

Ogun ẹjẹ pataki fun imarale agba ati arẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun inarun, ẹjẹ dudu, iṣokun oju, gbigbọn ọwọ, aile un, ailokun ninu ati irulẹ ara bawọnni. O jẹ ajidewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. On naẹ gan ni ọkunrin yi lo ti o fi di "Afẹṣẹ ku bi ojo." 5/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/6d e.g. 7/- Post Free.

The Egba Trading Aradan Stores 112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute - Metta. Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.





Printed Published by The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street, Lagos P. O. Box 467 phone 23370